152 Agbára Wa, Ìrètí Wa, Ìgbẹ́kẹ̀lé Wa

(Òwe 14:26)

1. Jèhófà, o fún wa nírètí
èyí tí à ńṣìkẹ́.
Ìrètí yìí ńmúnú wa dùn
a fẹ́ sọ fáyé gbọ́.
Nígbà míì, ìṣòro ayé yìí
máa ńmú kí ẹ̀rù bà wá,
Ìrètí tó ńmú ọkàn yọ̀
kò wá lágbára mọ́.

(*ÈGBÈ*)
Agbára, Ìrètí
Ìgbẹ́kẹ̀lé wa.
O máa ńbá wa gbé 'ṣòro wa.
À ńwàásù, à ńkọ́ni,
ọkàn wa balẹ̀
torí ìwọ la gbẹ́kẹ̀ lé.

2. Jọ̀ọ́ Jèhófà, jẹ́ ká máa rántí
pé o wà léyìn wa,
'Gbà gbogbo lò ńtù wá nínú
tí ìṣòro bá dé.
Àwọn ìrònú tó ńmókun wá
lè mú k'írètí sọjí,
Wọ́n ńjẹ́ ká lè fi ìgboyà
kéde orúkọ rẹ.
(*Ègbè*)

(Tún wo Sm. 72:13, 14; Òwe 3:5, 6, 26; Jer 17:7.)

© 2016 Watch Tower Bible and Tract Society of Pennsylvania